**5.** Atipe awọn oke yio da gẹgẹbi owu-irun ti a gbọ̀n.

وَتَكُونُ ٱلْجِبَالُ كَٱلْعِهْنِ ٱلْمَنفُوشِ ٥

**6.** Ki o ri ẹniti oṣuwọn (iṣẹ rere) rẹ̀ ba tẹ̀ iwọn.

فَأَمَّا مَن ثَقُلَتْ مَوَٰزِينُهُۥ ٦

**7.** On oniyẹn yio wà ninu ijaiye ti yio dùn mọ ọ.

فَهُوَ فِي عِيشَةٍ رَّاضِيَةٍ ٧

**8.** Atipe ẹniti oṣuwọn (iṣẹ rere) rẹ̀ ba fuyẹ.

وَأَمَّا مَنْ خَفَّتْ مَوَٰزِينُهُۥ ٨

**9.** Aye ibugbe rẹ̀ ni ina Hãwiya.

فَأُمُّهُۥ هَاوِيَةٌ ٩

**10.** Atipe kini yio mu ọ mọ ina Hãwiya na?

وَمَآ أَدْرَىٰكَ مَا هِيَهْ ١٠

**11.** Ina kan ti o gbona janjan ni.

نَارٌ حَامِيَةٌۢ ١١

## *(102) Suratul - Takãsuru*

سُورَةُ التَّكَاثُرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Wiwa ọpọ (-owó-ọmọ-) lati fi ṣe iyanran, ṣẹ nyin lori (kuro nibi iranti Ọlọhun).

أَلْهَىٰكُمُ ٱلتَّكَاثُرُ ١

**2.** Titi ti ẹ fi wọ awọn sãre.

حَتَّىٰ زُرْتُمُ ٱلْمَقَابِرَ ٢

**3.** Kò ri bẹ, laipẹ ẹ mbọ wa mọ̀.

كَلَّا سَوْفَ تَعْلَمُونَ ٣

**4.** Lẹhinna kò tun ri bẹ ẹ, laipẹ ẹ mbọ wa mọ̀.

ثُمَّ كَلَّا سَوْفَ تَعْلَمُونَ ٤

**5.** Rara o, ti o ba ṣe pe ẹ mọ imọ̀ amọdaju ni.

كَلَّا لَوْ تَعْلَمُونَ عِلْمَ ٱلْيَقِينِ ٥

**6.** Dajudaju ẹ ba ri ina Jahimi.

لَتَرَوُنَّ ٱلْجَحِيمَ ٦

**7.** Lẹhinna dajudaju ẹ o ri i ni riri aridaju.

ثُمَّ لَتَرَوُنَّهَا عَيْنَ ٱلْيَقِينِ ٧

ثُمَّ لَتُسْـَٔلُنَّ يَوْمَئِذٍ عَنِ ٱلنَّعِيمِ ﴿٨﴾

**8.** Lẹhinna dajudaju a o bi nyin lẽrè nipa idẹra ni ọjọ na.

## (103) Suratul - 'Asri

سُورَةُ العَصْرِ

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

وَٱلْعَصْرِ ﴿١﴾

**1.** Mo fi akoko irọlẹ ('Asri) bura.

إِنَّ ٱلْإِنسَٰنَ لَفِى خُسْرٍ ﴿٢﴾

**2.** Dajudaju enia mbẹ ninu òfò.

إِلَّا ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّٰلِحَٰتِ وَتَوَاصَوْا۟ بِٱلْحَقِّ وَتَوَاصَوْا۟ بِٱلصَّبْرِ ﴿٣﴾

**3.** Ayafi awọn ẹniti nwọn jẹ onigbagbọ (ododo) ti nwọn si ṣe iṣẹ rere ti nwọn si ngba ara wọn niyanju ṣiṣọ ododo, nwọn si ngba awọn enia niyanju lati ni farada.

## (104) Suratul - Humasah

سُورَةُ الهُمَزَةِ

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

وَيْلٌ لِّكُلِّ هُمَزَةٍ لُّمَزَةٍ ﴿١﴾

**1.** Egbe ki o ma ba gbogbo abuni loju ẹni (Humasah) ati abuni lẹhin.

ٱلَّذِى جَمَعَ مَالًا وَعَدَّدَهُۥ ﴿٢﴾

**2.** Ẹniti o ko owó jọ ti o si nka a laka-tunka.

يَحْسَبُ أَنَّ مَالَهُۥٓ أَخْلَدَهُۥ ﴿٣﴾

**3.** Ti o nro pe owo on ni yio mu on ṣe gbere laiye.

كَلَّا ۖ لَيُنۢبَذَنَّ فِى ٱلْحُطَمَةِ ﴿٤﴾

**4.** Rara o, dajudaju a o fi sọkò sinu ina Hutamatu.

وَمَآ أَدْرَىٰكَ مَا ٱلْحُطَمَةُ ﴿٥﴾

**5.** Atipe kini ohun ti o le fi ina Hutamatu nã mọ ọ?